wọn ninu gbogbo agbara wọn: wọn o fi
ọwọ le ẹnu, etí wọn o si di. (Job 21:5;
Mika 3:7.)
17. Wọn o lá erupẹ bi ejò, wọn o si
jade kuro ninu ihò wọn bi ekòló ilẹ:
wọn o bẹru Oluwa Ọlọrun wa, wọn o
si bẹ̀rù nitori rẹ. (Psm 72:9; Isa
49:23; Deut 32:24; Psm. 18:45; Isa
59:19.)
18. Tani Ọlọrun bi iwọ, ti o ndárí ai-
ṣedede jì, ti o nré iyoku ini rẹ kọja?
Kii gbé ibinu rẹ̀ ró titi lae, nitori oun ni
inudidun si aanú. (Eks 34:7,9; Isa
43:25; Jer 32:41.)
19. Yoo yipada, yoo ni ìyọ́nú si wa;
yoo si tẹ aiṣedede wa ba; iwọ o si sọ
gbogbo ẹṣẹ wọn sinu ọgbun òkun. (Jer
50:20; Isa 38:17; 43:25; Jer 31:34.)
20. Iwọ o fi otitọ fun Jakọbu, aanu
fun Abrahamu, ti iwọ ti bura fun awọn
baba wa, lati ọjọ igbani. (Luk 1:55,72;
Deut 7:8,12.)

34

# NAHUMU

**(B.C. 713)**

ORI 1.

**Orin nipa agbara nla Oluwa.**

ỌRỌ-ÌMỌ niti Ninefe, Ìwé iran
Nahumu ara Elkosi. (Isa 13:1;
Hab 1:1; Nah 2:8; 3:7.)
2. Oluwa njowu, Ọlọrun si ngbẹsan;
Oluwa ngbẹsan, o si kún fun ìbínú;
Oluwa ngbẹsan ni ara awọn ọta rẹ̀, o si
fi ibinu pamọ fun awọn ọta rẹ̀. (Eks
20:5; Deut 4:24; 32:35,41; Psm.
94:1.)
3. Oluwa lọra lati binu, o si tobi ni
agbara, ni didasilẹ ki yoo dá eniyan
buburu silẹ: Oluwa ní ọ̀nà rẹ̀ ninu aaja
ati ninu ìjì, ìkuukuu awọsanma sì ni
ekuru ẹsẹ̀ rẹ̀. (Eks 34:6,7; Psm
103:8; Isa 29:6; Psm 104:3.)
4. O ba òkun wí, o si mu ki o gbẹ, o
si sọ gbogbo odò di gbigbẹ: Baṣani di
alailera, ati Karmẹli, ìtànná Lẹbanoni
si rọ. (Psm 106:9. Isa 33:9.)
5. Awọn òkè-nla mì nitori rẹ̀, ati
awọn oke kékèké di yíyọ́, ile ayé si
jona niwaju rẹ̀, ani ayé ati gbogbo
awọn ti ngbe inu rẹ̀. (Eks 19:18; Mika
1:4; Isa 24:1,20.)
6. Tani o le duro niwaju ìbínú rẹ̀?
tani o si le duro gba gbigbona ibinu rẹ̀?
a da ibinu rẹ̀ jáde bi iná, oun ni o si fọ
awọn àpáta. (Jer 10:10; Mal 3:2; Isa
66:15; 1 A.Ọba 19:11.)
7. Rere ni Oluwa, aabo ni ọjọ ìpọ́n-
jú; oun si mọ awọn ti o gbẹ́kẹ̀le e.
(1 Kro 16:34; Psm 28:8.)
8. Ṣugbọn ikún omi àkúnrékọjá ni
oun fi ṣe ìparun ibẹ naa de òpin, yoo si
lépa awọn ọta rẹ̀ lọ sinu òkùnkùn. (Isa
28:2,18; Psm 13:9,10.)
9. Kinni ẹ̀yin ngbiro si Oluwa? oun
o ṣe ìparun dé òpin, ìpọ́njú ki yoo dide
lẹẹkeji. (Psm 2:1; Isa 28:22.)
10. Nitori naà tí a bá ká wọn jọ bi
ẹ̀gún, ati sáà tí wọ́n bá mu àmupara bi
ọmuti, a o run wọn gẹgẹ bi koriko ti o
ti gbẹ de opin. (2 Sam 23:6; Mal 4:1.)
11. Ẹnìkan tí ọ̀dọ̀ rẹ jade wá, tí o
ńgbìrò ibi sí Oluwa, olugbimọ buburu.
(Ẹsẹ 9; Esk 11:2.)
12. Bayìí ni Oluwa wi; "Bì wọn tilẹ
lagbara, ti wọn si pọ̀ níye, ṣugbọn bayìí
ni a o ge wọn lulẹ̀, nigba tí oun o ba
kọja. Bi mo tilẹ ti pọn ọ loju, emi ki
yoo pọn ọ loju mọ́. (Isa 10:16
–19,33,34; 54:7,8.)
13. Nitori nisinsinyìí ni emi o fa
ajaga rẹ̀ kuro ni ọrun rẹ, emi o si dá

awọn ìdè rẹ wọnyìí ni aarin-meji." (Isa 9:4; Jer 2:20.)

14. Oluwa si ti fi àṣẹ kan lélẹ̀ nitori rẹ̀ pe, "Ki a ma ṣe gbọ orukọ, ati iran-diran rẹ mọ́: lati inu ile ọlọrun rẹ wa ni emi o ge ère finfin ati ère dida kúrò: emi o wa iboji rẹ; nitori ẹgbin ni iwọ." (Isa 46:1,2; Mika 5:13,14; Esk 32:22,23.)

15. Wo o lori oke nla ẹsẹ ẹni ti o mu ihinrere wá, ẹni ti o nkede alaafia! Iwọ Juda, pa aṣẹ rẹ ti o ni ìrònú mọ́, san ẹ̀jẹ́ rẹ: nitori eniyan buburu ki yóò kọja laarin rẹ̀ mọ́; a ti ge e kuro pátápátá. (Isa 40:9; Psm 52:7; Lef 23:2,4; Isa 52:1; Joel 3:17; Isa 29:7,8.)

## ORI 2.

**Ìṣubú Ninefe.**

ATÚNIKÁ de iwaju rẹ (Ninefe): pa ile-ìṣọ́ mọ, ṣọ́ ọ̀nà naa, di amure ẹ̀gbẹ rẹ kó le, mura gírígírí. (Jer 51:20–23; Neh 3:12,14.)

2. Nitori Oluwa tun mu ọlanla Jakọbu pada, gẹgẹ bi ọlanla Israẹli: atunidànù ti tu wọn danu, wọn si ba ẹ̀ka ajara wọn jẹ. (Isa 60:15; Esk 37:21–23.)

3. A sọ asà awọn ọkunrin alagbara rẹ̀ di pupa, awọn akin wọn wọ òdòdó; kẹ̀kẹ́ ogun yoo maa kọ bi ina ni ọjọ imurasilẹ rẹ̀, igi firi ni a o si mi tìtì. (Esk 23:14,15; Job 39:23.)

4. Ariwo kẹkẹ ni igboro, wọn o si maa gbun ara wọn ni ọna gbígbòrò, wọn o dabi ẹ̀fúùfù, wọn o kọ bi mànàmáná. (Esk 26:10; Jer 4:13.)

5. Oun o ṣe àṣàrò lori awọn ọlọ́lá rẹ̀: wọn o kọsẹ ni ìrìn wọn; wọn o yara si ibi odi rẹ̀, a o si pèsè aabo rẹ̀. (Nah 3:18; Jer 46:12.)

6. A o ṣi ilẹkun awọn odò naa sílẹ̀, a o si sọ aafin naa di yíyọ́. (Nah 3:18.)

7. Eyi ti a ti fi ìdí rẹ̀ mulẹ ni a o si di ni ìgbèkùn lọ, a o si mu un gòkè wá, ati awọn iranṣẹbinrin rẹ̀ yoo fi ohùn bi ti oriri ṣọ̀fọ̀ rẹ̀, wọn a maa lu àyà wọn. (Isa 59:11; 32:12.)

8. Ṣùgbọ́n Ninefe ni ọjọ ti o ti wà bi adágún omi: sibẹ wọn o salọ kuro. Duro, duro! ni wọn o maa ké; ṣugbọn ẹnikan ki yoo wo ẹ̀hìn. (Nah 3:7; Jer 46:5; 47:3.)

9. Ẹ ko ìkógun fàdákà, ẹ ko ikogun wura! Nitori iṣura wọn kò lopin, pẹlu ogo ati ọrọ̀ awọn ohun ọ̀ṣọ́ iyebíye.

10. O ti ṣófo! O ti di ahoro! O si di asán! Ọkàn si daku, eekún nlu ara wọn, ìrora pupọ sì wà ninu gbogbo kinniun, ati oju gbogbo wọn si rẹ̀wẹ̀sì. (Psm 22:14; Isa 13:7,8; Joel 2:6.)

11. Nibo ni ibùgbé awọn kinniun wà, ati ibujẹ awọn ọmọ kinniun, nibi ti kinniun, ani àgbà kinniun ti nrin, ati ọmọ kinniun, kò sì sí ẹni ti o dẹruba wọn? (Isa 5:29; Jer 4:7; Neh 3:1.)

12. Kinniun ti faya pẹ́rẹpẹ̀rẹ tẹrun fun awọn ọmọ rẹ̀, o si fun ni ọrùn pa fun awọn abo kinniun rẹ̀, o si fi ohun ọdẹ kun isà rẹ̀, ati iho rẹ̀ fun ounjẹ agbara. (Isa 10:6–14; Jer 51:34.)

13. Kiyesi i, emi dojúkọ ọ, ni Oluwa awọn ọmọ ogun wí, emi o si fi awọn kẹ̀kẹ́ rẹ wọnyìí jóná nínú eefin, idà yoo si jẹ awọn ọmọ kìnnìún rẹ run; emi o si ge ohun ọdẹ rẹ kuro lori ilẹ ayé, ohùn awọn ojiṣẹ rẹ ni a ki yoo sì tun gbọ́ mọ́. (Nah 3:5; Psm. 46:9; Isa 49:24,25.)

## ORI 3.

**Awọn ìdí ti a fi pa Ninefe run.**

ÈGBÉ ni fun ilu ẹ̀jẹ̀ naa, gbogbo rẹ̀ kún fún èké, ati olè, ìgárá kò kuro; (Esk 24:6,9.)

2. Ariwo pàṣán, ati ariwo kíkùn kẹ̀kẹ́, ati ti ijó awọn ẹṣin, ati ti fífò kẹ̀kẹ́. (Nah 2:3,4; Jer 47:3.)

3. Ẹlẹṣin ti gbe idà rẹ̀ ti nkọ mànà, ati ọ̀kọ̀ rẹ̀ ti ndan yanran sí oke: ọpọlọpọ sì ni awọn ẹni ti a pa, ati ọpọlọpọ sì ni okú-èèyàn, òkú kò lópin; bẹẹ ni wọn n kọsẹ lori awọn òkú wọn. (Hab 3:11; Isa 34:3; 2 A.Ọba 19:35.)

4. Nitori ọpọlọpọ iṣe-panṣaga ti panṣága-obinrin afetàn-múni, iyá àjẹ ti nta

awọn orilẹ-èdè nipaṣẹ panṣaga rẹ, ati awọn ẹbí nipaṣẹ iṣe-àjẹ́ rẹ̀. (Isa 23:17; Ifh 17:1,2; Isa 47:9; Ifh 18:3.)

5. Kiyesi i, emi dojukọ ọ, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wi; emi o si ká yẹ̀rì-ìdí rẹ sí oju rẹ, emi o si fi ìhòhò rẹ han awọn orilẹ-èdè; ati ìtìjú rẹ han awọn ilẹ ọba. (Nah 2:13; Isa 47:2,3; Jer 13:22; Esk 16:37.)

6. Emi o da ẹ̀gbin ti o ni ìríra si ọ lára, emi o si sọ ọ di aláìmọ́, emi o si gbe ọ kalẹ bi ẹni ifiṣe ẹlẹya. (Job 9:31; Mal 2:9; Isa 14:16; Jer 51:37.)

7. Yoo si ṣe pe, gbogbo awọn ti o wò ọ yoo sá fun ọ, wọn o si wi pe, a ti fi Ninefe ṣòfò: tani yoo kẹ́dùn rẹ̀? nibo ni emi o ti wá olùtùnú fun ọ? (Jer 51:9; Nah 2:8; Sef 2:13; Isa 51:19; Jer 15:5.)

**Idajọ ti o tọ́.**

8. Iwọ ha sàn jù No-ammoni, eyi ti o wà laarin odò ti omi yika kiri, ti agbara rẹ̀ jẹ́ òkun, ti odi rẹ si ti inu òkun jáde wá? (Jer 46:25; Esk 30:14–16; Isa 19:6–8.)

9. Etiopia ati Egipti ni agbara rẹ̀, kò si ni òpin; Puti ati Lubimu ni awọn olùrànlọ́wọ́ rẹ. (Isa 20:5; Esk 27:10; 30:5; 38:5; 2 Kro 12:3; 16:8.)

10. Sibẹsibẹ a kó o lọ, o lọ si oko-ẹrú: awọn ọmọ wẹ́wẹ́ rẹ̀ ni a fi ṣánlẹ̀ pẹlu ni ori ìta gbogbo; wọn si di ìbò ni-tori awọn ọlọla rẹ ọkunrin, gbogbo awọn ọlọla rẹ̀ ni a si fi ẹ̀wọn dì. (Isa 20:4; 13:16; Hos 13:16; E.Jer. 2:19; Joel 3:3; Obad 11.)

11. Iwọ pẹ̀lú yoo mu ọti yó, a o si fi ọ pamọ, iwọ pẹlu o si maa ṣe afẹri ààbò nitori ti ọ̀tá naa. (Jer 25:27; Isa 2:10,19.)

12. Gbogbo ile-ìṣọ́ agbara rẹ yoo dabi igi ọ̀pọ̀tọ́ pẹlu àkọ́pọ́n ọ̀pọ̀tọ́: bi a ba gbọ̀n wọ́n, wọn o si bọ si ẹnu ọ̀jẹun. (Isa 28:4; Ifh 6:13.)

13. Kiyesi i, obinrin ni awọn ogun rẹ laarin rẹ: oju ibodè ilẹ̀ rẹ ni a o ṣi silẹ gbagada fun awọn ọ̀tá rẹ: ina yoo jo ọ̀pa-ìdábu rẹ. (Jer 50:37; 51:30; Psm 147:13.)

14. Iwọ pọn omi de ihamọ, mu ile-ìṣọ́ rẹ le: wọ inu iho-amọ̀, ki o si tẹ erùpẹ̀, ki o si ṣe ibi ti a nsun bíríkì-amọ̀ ki o le. (2 Kro 32:3,4,11; Nah 2:1.)

15. Nibẹ ni iná yoo jo o run; idà yoo gé ọ kuro, yoo si jẹ ọ́ bi kòkòrò: sọ ara rẹ di pupọ bi kòkòrò, si sọ ara rẹ di pupọ bi eeṣú. (ẹsẹ 13; Joel 1:4.)

16. Iwọ ti sọ awọn oníṣòwò rẹ di pupọ ju ìràwọ̀ ojú ọrun lọ: Eeṣú si na iyẹ rẹ̀, o si fò lọ. (Isa 23:8.)

17. Awọn alade rẹ̀ dabi ẹlẹnga, awọn ọgagun rẹ̀ si dabi eeṣú, eyi ti ndo sinu ọgbà ni ọjọ́ òtútù, ṣugbọn nigba ti oorùn là, wọn sá lọ, a kò si mọ ibi ti wọn gbe wà. (Jer 51:27; Ifh 9:7.)

18. Awọn òlùṣọ́-àgùtan rẹ ntoògbé, Iwọ ọba Assiria: awọn ọlọ́lá rẹ yoo maa gbe inu ekuru: awọn eniyan rẹ si tuka lori òkè-nla, ẹnìkan kò si kó wọn jọ. (Psm 76:5,6; Isa 56:10; Jer 51:57; Nah 2:5; 1 A.Ọba 22:17.)

19. Kò si ipajumọ̀ fun ifarapa rẹ; ọgbẹ́ rẹ kún fún irora, gbogbo ẹni ti o gbọ ìhìn rẹ yoo pàtẹ́wọ́ le ọ lori Nitori ni ori tani ìwà-buburu rẹ koi ti kọja nígbàgbogbo? (Mika 1:9; E.Jer. 2:15; Sef 2:15.)